AWỌN ASỌTẸLẸ NIPA IBI KRISTI

Numeri 24:17; Isaiah 7:14; 9:1-7; 11:1-5; Mika 5:2;

Jeremiah 31:15

ẸKỌ 103 – FUN AWỌN ỌDỌ

AKỌSORI: "Jesu ni iwọ o pè orukọ rẹ; nitori on ni yio gbà awọn enia rẹ là kuro ninu ẹṣẹ wọn" (Matteu 1:21).

ALAYE

Irawọ Kan ni Ila-Oorun

Ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, irawọ daradara ti o mọlẹ pupọ yọ ni oju ọrun. Awọn amoye ila-oorun ri irawọ naa, wọn si gbagbọ pe irawọ yii n sọ nipa ti ibi Ọba awọn Ju (Matteu 2:1, 2; Numeri 24:17). Boya wọn ti kọ ẹkọ lati inu Iwe Mimọ, wọn si ti ri pe awọn wolii ti sọ asọtẹlẹ nipa Ọba ti o n bọ wá. Dajudaju, wọn ti kà a pe a o bi ọmọ kan ti yoo maa ṣe akoso ijọba (Isaiah 9:6; 7:14). O to akoko lati bi ọba naa (Danieli 9:25), o si daju pe irawọ yii tobi, o si mọlẹ ju gbogbo irawọ miiran ti wọn ti ri lọ, nitori naa wọn rin irin-ajo lọ si Jerusalẹmu nibi ti ọba Herọdu n gbé (Matteu 2:1). Ẹ wo iru ijatilẹ ti wọn ni, nigba ti wọn ko ri ọmọ-ọwọ kan rara ninu aafin. Ṣugbọn Herọdu pe awọn akọwe ati awọn alufaa, o si beere lọwọ wọn, ohun ti wọn mọ nipa ibi ọba kan. Wọn sọ fun un pe, wolii kan ti wi pe a o bi Kristi ni Bẹtlẹhẹmu (Mika 5:2; Matteu 2:4-6).

Ẹbun fun Jesu

Awọn amoye naa yara lọ lati wá Ọmọ-ọwọ naa. Bi wọn ti fi aafin silẹ, irawọ daradara naa wà sibẹ, o si n lọ siha Bẹtlẹhẹmu. Bawo ni inu wọn ti dun to, nitori o ṣe amọna wọn lọ si ọdọ Ọmọ-ọwọ naa. Bi wọn ti sunmọ tosi, ti wọn si ri Ọmọ-ọwọ naa ati Maria iya Rẹ, wọn si fori balẹ fun Un.

Wọn ti mu ẹbun wa, nitori naa wọn tú iṣura wọn eyi ti i ṣe wura, turari ati ojia. Awọn wọnyii jẹ ọrẹ ti o lowo lori lọpọlọpọ, ṣugbọn wọn fẹ fun Jesu ni ohun ti o dara ju lọ ninu nnkan ti wọn ní.

Ni owurọ Keresimesi kin-in-ni yii, Ọlọrun fun araye (ati awa naa pẹlu) ni iṣura ti o tobi ju lọ ni Ọrun, Ọmọ Rẹ (Johannu 3:16). Bi awọn amoye wọnyii ti sin In, ti wọn si fi ẹbun wọn fun Un, bakan naa ni awa gbọdọ ṣe pẹlu. Ẹbun wa ki i ṣe fadaka ati wura tabi ọṣọ iyebiye, ṣugbọn ohun ti o dara ju lọ ti a ni – aye wa ati ifẹ wa.

Kò Si Àye fun Jesu

Awọn obi Jesu, Maria ati Josẹfu ti fi ilu wọn Nasarẹti silẹ, wọn si ti lọ si Bẹtlẹhẹmu lati lọ fi orukọ silẹ. Nitori idile Dafidi ni wọn i ṣe (Luku 2:4), wọn lọ si ilu Dafidi (Bẹtlẹhẹmu). Ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, awọn wolii ti wi pe, ki i ṣe pe a o bi Kristi ni Bẹtlẹhẹmu nikan (Mika 5:2), ṣugbọn Oun yoo wá gẹgẹ bi Ẹka lati idile Jesse (Isaiah 11:1). Jesse ni baba Dafidi (1 Samuẹli 16:1-13). Lẹyin naa Jesu tikara Rẹ wi pe lati idile Dafidi ni Oun ti wá (Ifihan 22:16).

Eniyan pupọ ni o ni lati wà nibẹ, nitori gbogbo àye ti o wà ninu ile-ero ni o ti kún, ṣugbọn Maria ati Josẹfu ri àye ni ibujẹ ẹran. Nigba ti a bi Jesu, ko si ẹni kan ti o fi ibusun rẹ fun Jesu. Bawo ni o ti jẹ itiju tó pe Ọmọ Alade Alaafia ko ni ibusun, ayafi koriko! Ṣugbọn awọn miiran lonii ko ni aye fun Jesu ninu ọkàn ati ayé wọn. Wọn ti le E lọ gẹgẹ bi onile-ero nì ti ṣe, wi pe "Kò si aye." Njẹ o ní aye fun Jesu ninu ọkàn rẹ?

Lai pẹ Jesu tun n pada bọ wa sinu ayé lọjọ kan. Awọn miiran yoo ri I, wọn yoo si sin In. Wọn wa ni imurasilẹ, wọn si n reti Rẹ. Ki i ṣe ọpọ eniyan ni o ri Jesu nigba ti a bi I ninu ibujẹ ẹran. Wọn kò wọna fun Ọba naa, gẹgẹ bi awọn amoye wọnni ti ṣe. Wọn ko reti Rẹ, nitori naa, wọn padanu Rẹ. Awọn ti wọn kò reti Rẹ lakoko yii yoo padanu Rẹ pẹlu. A bá lè dabi awọn amoye nì -- ki a maa wọna fun Jesu! Bi Jesu ba de lonii, njẹ iwọ yoo ha wa ni imurasilẹ lati pade Rẹ?

Awọn Oluṣọ-Agutan

Ki i ṣe awọn amoye wọnyii nikan ni wọn ri Kristi Ọmọ-ọwọ naa, nitori awọn oluṣọ-agutan ti lọ sin In ṣiwaju akoko yii. Bi wọn ti n ṣọ awọn agutan wọn, ogo Ọlọrun tàn si ori oke naa, angẹli kan si sọ Ihinrere ayọ ti ibi Olugbala fun wọn. Oju ọrun kun fun awọn angẹli ti wọn n yin Ọlọrun logo pe, "Ogo ni fun Ọlorun loke ọrun, ati li aiye alafia, ifẹ inu rere si enia" (Luku 2:13, 14).

Nigba ti awọn angẹli naa lọ tan, awọn oluṣọ-agutan yii mọ pe Ọlọrun ni O ranṣẹ naa si wọn. Wọn yara lọ si Bẹtlẹhẹmu lati ri Ọmọ-ọwọ naa ti a ṣẹṣẹ bí, Ẹni ti wọn ri, ti o dubulẹ ni ibujẹ ẹran. Awọn oluṣọ-agutan wọnyii gba angẹli naa gbọ, wọn si ri Kristi, Ọmọ-ọwọ naa, gẹgẹ bi angẹli nì ti wi. Wọn fi tọwọtọwọ duro, o si daju pe wọn fori balẹ lati sin Ọmọ-ọwọ Mimọ naa. Wọn pada lọ, wọn si n fi ogo ati iyin fun Ọlọrun. Wọn sọ ohun ti a sọ fun wọn

fun awọn ẹlomiran, ati ohun ti wọn ti ri, ti wọn si ti ni iriri rẹ. Wọn dabi awọn ti wọn ba Jesu pade lonii. Wọn n fẹ sọ Ihinrere ayọ naa fun awọn ẹlomiran.

A Sọ Ọmọ-Ọwọ Naa Lorukọ

A fun Ọmọ-ọwọ naa ni orukọ pupọ. Ki a to bi I, Ọlọrun wi pe a o pe E ni Jesu nitori Oun ni yoo gba awọn eniyan Rẹ la kuro ninu ẹṣẹ wọn (Matteu 1:21). Nigba ti Ọlọrun ba Josẹfu ọkọ Maria sọrọ, O wi fun un pe, a o pe Jesu ni "Emmanuẹli" pẹlu, Itumọ eyi ti i ṣe "Ọlọrun wà pẹlu wa" (Matteu 1:23; Isaiah 7:14).

Ninu Isaiah 9:6, a ka a pe, a o maa pe E ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia." Ninu awọn orin ti a n kọ n tọka si Jesu gẹgẹ bi "Itanna Ipado;" "Itanná Eweko Ṣaroni' (Orin Solomoni 2:1). "Apata Aiyeraiye" (1 Kọrinti 10:4), ati Oluṣọ-agutan rere" (Johannu 10:11). Njẹ iwọ tun mọ awọn orukọ miiran ti a fi n pè É?

Ète Ti O Kuna

Hẹrọdu ti sọ fun awọn amoye wọnni pe ki wọn jẹ ki oun mọ̀ nigba ti wọn ba ri Kristi Ọmọ-ọwọ naa. O fi ọgbọn ẹtan wi pe oun fẹ lọ sin In pẹlu. Ṣugbọn Ọlọrun mọ ohun ti o wà ninu ọkàn buburu Hẹrọdu, ti o kun fun owú, nitori naa O kilọ fun awọn amoye naa. Wọn ko si pada sọdọ Hẹrọdu, ṣugbọn wọn ba ọna miiran pada lọ si ilu wọn. Nigba ti Hẹrọdu ri i pe ẹtan oun ko lagbara lori wọn, inu bi i nitori ẹlẹṣẹ, ati eniyan buburu ni oun i ṣe. O pinnu lati pa Jesu, nitori naa o fi aṣẹ lelẹ pe ki a pa gbogbo awọn ọmọ kékèké ti wọn ko ti i to ọmọ-ọdun meji. O ro pe nipa ṣiṣe bẹẹ, o daju pe oun yoo pa Jesu, Ọba awọn Ju. Ẹru ba Hẹrọdu pe oun yoo sọ ipò oun nù, nitori naa ni o ṣe ṣeto lati pa Jesu. Ibanujẹ ati ikaanu kun ọkan awọn eniyan, nipa iṣe eniyan buburu kan ti o kun fun owu. Sa ronu bi a o ti sọkun pupọ tó bi a bá pa gbogbo awọn ọmọde ti wọn kò ti i to ọmọ ọdun meji lonii!

Eyi ni akoko ti wolii Jeremiah sọ nipa rẹ nigba ti o wi pe ibanujẹ ati ẹkun pupọ ni yoo wà nitori awọn ọmọde ti ko si mọ́ (Jeremiah 31:15; Matteu 2:16-18). Ko si ẹni ti o le pete lodi si eto Ọlọrun ki o bori. Ọkàn Hẹrọdu le, o si kun fun ipaniyan, ṣugbọn ete ọkan rẹ yii lati pa Jesu kùnà. Ọlọrun kilọ fun Josẹfu lati gbe Ọmọ-ọwọ naa ati Maria lọ si Egipti nibi ti wọn wa titi ikú Hẹrọldu. Lọna bayii, a mu Iwe Mimọ ṣẹ, nitori a kà a pe Ọlọrun pe Ọmọ Rẹ lati Egipti jade wá (Hosea 11:1).

AWỌN IBEERE

1. Ilu wo ni a ti bi Jesu?
2. Bawo ni awọn amoye ṣe mọ ibi ti wọn yoo ti ri I?
3. Bawo ni awọn oluṣọ-agutan ṣe mọ pe a ti bi Jesu?
4. Ki ni ṣe ti a bi I si ibujẹ ẹran?
5. Iru eniyan wo ni Hẹrọdu i ṣe?
6. Sọ diẹ ninu awọn asọtẹlẹ ti awọn wolii sọ nipa ibi Jesu.
7. Iru ẹbun wo ni iwọ yoo fi fun Jesu lakoko Keresimesi yii?